ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE-WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 890 LAGOS SATURDAY OCTOBER 11 — OCTOBER 18 KỌBỌ MEJI (2D) 1963.

## Isele Pa Egberun Enia Ni Ilu Itali:

# Ekunmi Fe Pa Ilu Itali Re

ROME—Ojojumọ ni aiye nparẹ diẹdiẹ. irohin ti a gbọ ni osan ana nipa awọn ogunlọgọ enia ti iṣẹlẹ kan pa ni agbegbe ilu Rome ni Itali nibiti nwọn gbe ti nṣe iṣẹ idari omi. A gbọ wipe nibi nwọn gbe ti nṣe iṣẹ idari omi odo sisan (DAM) ni ogiri nla kan ti wo ti o pa ogunlọgọ enia.

Awọn Ọlọpa si wa ninu iṣẹ gbigbe awọn oku ti nwọn ku na, nwọn ni nwọn le ju iye ti awọn ro wipe o ku sibi iṣẹlẹ na lọ.

# Achara Asoju Ijoba Fowo Taran Nilu Oyinbo

LONDON—Ọgbẹni Chinyere Achara, ẹni ọdun mẹrinlelogoji ti awọn alamojuto Ijọba Ipinlẹ Ila Orun fi igba kan ran lọ si ilu Oyinbo gẹgẹbi aṣoju Ijọba wọn ni ilu Gẹsi ni a gbọ wipe adajọ Kotu awọn ọlọpa ilu London ni ki o fi pọnun mọkanleladọta ati ṣile mewa taran fun ibọn ilewọ ati awọn ọta ibọn ti awọn Ọlọpa ni awọn ka mọ ọ lọwọ.

Ọga ọlọpa, Ọgbẹni Ian Payne, sọ fun adajọ ti nwọn ro ẹjọ ni iwaju rẹ wipe ọdaran Achara fẹran a ngbe ibọn ilewọ (revolver) kiri ọdọ awọn onile rẹ ti o ba fẹ gbowo oṣu lọwọ wọn, a si ma fi dẹru ba wọn wipe ẹniti ko ba san owo fun on, on a pa a lapafọn.

Awọn ọlọpa ni ọdaran ra ile kan ni ilu Oyinbo ti o fi nṣe owo ṣiṣe oju ẹgbẹrun pọnun ti ọdaran na i ri gba lori ile na lọdọdun, ko tile fẹmọ ẹnikan lẹnikan ninu awọn ti o iu sinu ile na gbogbo wọn ni o nfi ibọn ati ọta ibọn dẹruba.

Ọkan ninu awọn ọmọ ilẹ Nigeria, Ọgbẹni Christian Idowu, ti o fi iyara kan haya fun sọ fun

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Ijoba Torunbo Pakute Lori Owo Ile: Awon Osise Ni Awon Ko Ni San-wo Fun Onile Losu Yi

EKO— Ọrọ tun bẹhin yọ lọdọ awọn oṣiṣẹ ile Ijọba ati nile iṣẹ awọn onișowo ni irọlẹ ana nipa owo ile hihaya ti awọn oṣiṣẹ na ngbe l'Eko, ni Ebute Metta, Yaba, Suru-Lere, Abule Ọja ati Apapa Ajegunlẹ. Nwọn ni owo ile mehaya ti awọn nsan ni oṣoṣu pọ, awọn ni bi awọn alamojuto eto iṣẹ Ijọba ko ba ba awọn ri si bi nwọn yio ti ṣe ofin lati din awọn owo ile na ku, awọn ko ni san epinni fun awọn onile Eko loṣu yi rara.

Awọn onirohin wa ni on gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ mehaya kan ti nwọn nje Nigerian Tenants Union ti ṣe ipade nla kan lori ọrọ na nwọn si ti ranṣẹ si gbogbo awọn ọmọ egbẹ wọn ti nwọn wa ni idalẹ bi Ibadan, Enugu Kaduna Port — Harcourt Kano ati Jos wipe ki awọn na mura silẹ lori ọrọ awọn onile mehaya ti nwọn nfi owo-ile wọn ni awọn lara loṣoṣu yi.

Mo gbọ wipe nwọn ni awọn ko fẹ ki ọrọ awọn na ba awọn alamojuto eto iṣẹ Ijọba na abo, nitorina wọn ti kọwe lori ipinnu wọn si Minisita ti o wa fun eto arin ilu Eko ti nwọn npe orukọ rẹ ni Malam Yar' Adua.

Nwọn ni ogun agbọtẹtẹ ki pa arọ. Nwọn ni o ti to iwọn nkan bi ọdun mejila nisisiyi ti awọn ti nkigbe lemọ-lemọ fun alamojuto eto iṣẹ Ijọba wipe ọna ti awọn onile Eko fi mbu owo si owo-ile ti awọn nhaya lọwọ wọn ko lẹgbẹ,

Awọn ọmọ ẹgbẹ mehaya ile ni ivara ti ko ju pọnun meji abọ lọ ni awọn nsan pọnun mẹta abọ fun. Wọn ni ni ibomiran ile ti nwọn ni lati gba ṣile mẹdogun fun ọkẹ mẹsan ṣile ni awọn alailanu onile nwọnyi ngba lọwọ awọn loṣoṣu.

(Wo yoku loju ewe kejọ)

## Owo Ile Mehaya Fe Da'ja Sile Larin Awon Oga Osise

EKO—Ọrọ owo ile hihaya mehaya oṣiṣẹ ni ki awọn aṣiwaju awọn fi sinu iwe ti awọn fẹ fi si iwaju awọn oluwadi lori nkan pa aki ti awọn ṣe binu da iṣẹ silẹ, ti awọn aṣiwaju wọn na fo lati fi sinu iwe iwadi na fẹ dọran nla silẹ lari awọn oṣiṣẹ ati awọn asiwajn wọn.

(Wo yoku loju ewe kejọ)

# Omo Kan Nfero Mi

STOCKHGLMI— Awọn dokita Oyinbo ṣe okan ara fun ọmọde kan ẹni odun mẹdogun ti orukọ rẹ njẹ Christain Olesen, ti nwọn ni agbara mimi ẹmi rẹ ko to fun un.

Nk n ara ti awọn dokita Oyinbo na ti n ṣe ni wipe ẹrọ kẹkere kan nwọn na waya batiri ẹlẹtiriki si ti nwọn ran ọmọ na aya, ti o ba si ti nmi batiri yi pẹlu waya ẹlẹtiriki a ma ṣe iṣẹ lara ẹ.

A gbọ wipe o ti di ọdun meji gbako n s si ti awọn dokita na ti ṣe iṣẹ yi fuu un, ṣugbọn nwọn mu ọm na lọ si ile iwosan awọn dokita na lana fun ibẹwo, nwọn ni o yẹ ki nwọn yẹ ẹ wo boya diẹ ninu awon waya ti awọn ta sara rẹ, ti nye diẹdiẹ nitoripe ọkan ọmọ na ko lu kiki bi o ti nlu mọ.

Awọn dokita na si wa lẹnu wipe wọn nwo ọna bi o ba wa jaiye ni nko ba ọṣe abiku agba.

# Britain's First Space Craft



The first all-British setellite, U. K. 3, is scheduled for launching in 1966 carrying five scientific experiments into a circular orbit 400 miles above the earth.

# Awon Tisa Ti O Ju Ise Sile Pada

CONGO—Ogunlọgọ awọn tiṣa ilu Congo ti nwọn ti fi igba kan da iṣẹ sl i a gbọ wipe nwọn ti pinnu lati padi si ibi iṣẹ wọn ni ara nigbati awọn onilaju kan dide si ọrọ awọn tisa na pẹlu awọn alakoso Ijọba ilu na.

G gẹbi irohin ti a gbọ nipa nkan ti a sababi dida iṣẹ silẹ na, a gbọ w to iwọn nkan bi oṣu mẹfa n- s awọu tiṣa olukọni na ko ti ri o su wọn gba rara.

N bati ebi bẹrẹsi pa awọn ọmọ ati y wo wọn, nwọn fi ọrọ na sun aw alakoso Ijọba wipe awọn koi to o iṣẹ awọn gba lọdọ awọn alakoso le igbimọ ti nwọn ni lati san owo fun awọn.

O le ni ọkẹ kan o le ẹdẹgbajọ (35,000) awọn tisa na ti nwọn binu fi s silẹ lọkunrin ati lobinrin, sugbọn n ti pinnu lati pada sẹnu iṣẹ nigbati n ọn ni nwọn yio san abọ owo oṣu wọn fun wọn ninu oṣu yi.


E ma ka

Iwe Irohin

Eleti-Ofe

To kun fun irohin aladun

Losose

# Kiko Ila Ereke (1)

**Lati Owo Alufa Atilade**

Ọkan ninu awọn aṣa ti o fi idi mulẹ larin awọn Yoruba igba lailai ni aṣa kiko ila ẹrẹkẹ. Bi ẹnikan ko ba kọ ila, o jẹ ohun abuku fun oluwa rẹ pe awọn obi rẹ ko ri owo kọ ila fun un. Awọn ẹgbẹ rẹ papa yio ma lu u ni ẹkọkan, nwọn yio si ma bu u pe— "A bi ẹrẹkẹ jẹ alabẹ ni gbese."

Diẹ ninu awọn ila wọnyi ti a nkọ ni Ilẹ Yoruba wọnyi:- Pele, Abaja, Gọmbọ, Kẹkẹ, Abaja—Olowu, Ture, Ifọn, Ondo, Benin Bamu.

Ọkan ninu awọn idi ti o mu ki asa ila kiko gbile pupọ larin awọn Yoruba ni owo ẹru. Ni akoko owo ẹru, ila kikọ wulo pupọ.

Ni igba lailai, a le mu enia kan ni Ibadan ki a si ta a si agbegbe Abẹokuta tabi Ijẹbu-Ode, Ifẹ awọn ẹbi ẹniti a mu lẹru yi lati wa ọmọ wọn ri ati lati ra a pada.

Bi ẹniti a mu l'ẹru yi ba kọ ila ẹrẹkẹ, pẹlu irọrun ni a fi le wa a ri; ṣugbọn ti ko ba kọ ila, o ṣoro lati le wa a ri. Bi a tilẹ ri i nigbamiran, on papa le ma ni ami ti yio fi le mọ awọn obi rẹ. Nitorina, ila kikọ wulo pupọ ni igba lailai lati wa awọn ẹniti a mu ni ẹru ri.

Ila kikọ tun wulo lati fi idile Ọba han yatọ si awọn idile miran ninu ilu kanna. Fun apẹre, awọn idile Ọba ni Ọyọ a ma bu abaja. Ninu ile Ọba ni bi ti awọn Ọmọ Ọba ngbe pọ pẹlu awọn ọmọ ẹru, a ma fi iyatọ si arin wọn nipa kikọ ila iyatọ fun awọn ọmọ ẹru.

Ki ila idile ba le ma ba ara wọn mu [illegible] kanna, awọn obi ama fẹ ṣe olola kanna lati [illegible] fun awọn ọmọ wọn. Olola yi papa yio tun fi [illegible] balẹ lati ṣe akiyesi bi ila baba ọmọ na [illegible], yio si kọ ila ọmọ na gẹgẹbi ti baba rẹ. Bi awọn agbalagba ba wo ọmọ kan sunsun, nwọn a bere pe, "Nj[illegible] ọmọ lamọrin ki ẹ?" Nigbati ọmọ yi ba dahun pe", Bẹ[illegible],

(Koi pari)

Advert No 207

## SPECIAL ANNOUNCEMENT

WIRELESS AND TELEVISION LICENCES 1963

Have you bought your Radio and Television Licence for 1963? If not, please note that the Posts and Telegraphs, Investigation Branch has started to prosecute Radio and Television Licence Defaulters. Buy your 1963 Licence today at Post Office. It is cheaper to licence your Radio and Television Sets than to pay a fine of Fifty Pounds.

N. V. KNIGHT.
Director,
POST & TELEGRAPHS

# Eleti—Ọfẹ D'araba

Fun ina dida ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE
KEROSINE
L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'oye o le [illegible] nibikibi, ko si wọn, o mọ daradara, owun [illegible] dara ju fun onje-sise, iná-titàn ati lati mã fi [illegible] Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP Ju gbogbo wọn lọ!

# ELETI-OFE

A NJU WỌN KOSE WILẸJỌ )

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 870 SATURDAY OCT 11 - OCT 18, 1963


## Oro Olotu:

# Iwa Alailo-juti

Bi ojumọ ti nmọ ni ọkanjuwa ndagba si Isrin awọn ọmọ araiye nisisiyi. O ni a gbọ wipe ..l.fa Ijọ ko. o jẹ. Ọla a gbọ wipe Lemọnu lu o vo awọn Jaumọ rẹ ni ... npo nitori ọna ọfun, ọna ọrun.

I.a alailojuti wọnyi bẹrẹ lọdọ awọn agba agba, awọn .a ṣe tan nwọn ko o ran awọn ọmọde ti o fi jẹ wipe ẹnikẹni ko fẹ ro nkankan ti on le fi ran aladugbo .n lọwọ mọ a fi ọna bi on yio ṣe rẹjẹ, ti on yio ko nkan tirẹ mọ t'on.

Bi ko bi ṣe iwa alailojuti kinni orukọ ti a le fun iwa awọn ikọ ti a ran lọ lọ si ile igbimọ, ko ba jẹ igbimọ Ijọba ibile tabi ti aṣofin ni, ti nwọn de ọhun tan ti nwọn nna ọpa itẹlẹ mọ ara wọn lori, ti nwọn ... iwe iṣẹ ajọ igbimọ na danu?

B. enyin ni ba pade awọn ọdọ .ọde kan ti nwọn hu ..wa bayi yala ninu ile ẹkọ ni tabi nibi apejọ ... ọn, e mọ orukọ ti ẹ o pe nwọn ni ALAILẸKỌ T.. .MỌ ITA. Ṣugbọn nigbati awọn bale onilelọna ba ..hu ir. iwa eyi suna wo ni ẹ fẹ ki a fun wọn'ju ọ... ..awọn alailojuti lọ.

Ko ya wa lẹnu rara lati gbọ idi nbajọ ti o fa iru iwa bayi ti awọn kansilọ aṣoju wa ua hu nile ipade na ... Eleti-Ọfẹ ri wipe ọkanjua ni o fa gbogbo rẹ ṣugbọn a fẹ ki nwọn mọ pe awọn ara Eko .. ran wọn lọ sibẹ fuu ija ija, ki nwọn lọ ... ni ilu yi ... ṣe dara ti ita Eko yio mọ toto, ti awọn agbole ọja yio ṣe iṣẹ wọn deede ni a ran wọn lọ sibẹ fun.

# { Iwe Si Olotu }

# Dokita Maja Pe Omo Re Lejo

## Nitori Owo Ile

EKO— Dokita Akinọla Maja (Baba Eko) ti o fi igbakan je Baba Ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) pe ọmọ rẹ Dokita Ọladipọ Akinwunmi Maja lẹjọ ni ile ẹjọ .la kan l Eko, nitori ile ti o fi igbakan ni Ita-Akanni, ti ko san owo ile na fun odindi ọdun kan gbako.

Dokita Maja ni on fẹ ki adajọ ba on le ọmọ on na kuro ninu ile na, ki nwọn si ba on gba (£480) ẹgbẹrun ..dia-ogun pọnun lọwọ re, owo ile ọdun kan fun ọdun ti o ti lo koja, o ie pọnun marundinogoji loṣu (£35).

A gbọ wipe niwaju adajọ Ọgbẹni J. F. Shomẹfun ni nw.n o ti ro ẹjọ na ninu oṣu yi.

Dokita Maja Kekere je ọkan ninu awọn ti ọlọpa mu fun ẹsun otẹ si Ijọba ti wọn fi sun Oloye Awolọwọ ati ogun enia ki o to di ẹlẹrẹ kinni fun Ijọba.

## Owo Ile Yi Po

Ẹjọwọ ẹ gba mi laye lati tọka iwa buruku ti awọn onile Eko ma nhu lati gba owo gọbọyi lọwọ awa mehaya ti a si kigbe titi wipe ki awọn alamojuto Ijọba wa jọwọ gba wa lọwọ awọn onile nwọnyi ti nwọn nfun wa lọrun loṣoṣu.

A bẹ wọn ki nwọn jọwọ ba wa ṣe ofin lati din owo ile na titi, nwọn ko fẹ ṣe eyi fun anfani awa ti a ko ni owo lọwọ.

Ko si owo ti awọn oṣiṣẹ le gba kun owo wọn ti yio mu irọrun wa ju ki awọn alamojuto eto iṣẹ Ijọba din owo ile mehaya ku l'Eko, Ibadan, Kaduna, Kano, Enugu ati awọn ilu bi Port-Harcourt lọ. Eyi n o le mu inu awọn oṣiṣẹ duu jake jado.

Ẹ gba wa owo ile yi pọ ju o.

Emi ni,
Eko "Mehaya"



# Iyawo Alarede F'omo Osu Meta Sile, O Sun Sile Ale

IJẸBU-ODE—Kotu nla kun o fẹ ya ni ijẹjọ nigbati ọkọ iyawo alarede kan ti orukọ se njẹ Adewale Akinbọ Cole, olukọ nile ti nwọn ti nkọ awọn akẹkọ nisẹọwọ bẹrẹsi ro nkan ti iyawo ti o gbe larede ni iwọn odun mọkandilogun nfoju rẹ ri ni iwaju adajọ-agba Ọgbẹni V. Akin-Delumọ. Orukọ iyawo alarede na ni Frances Ọmọlayajọ Cole ẹni ogoji ọdun ni, ile kan ni Oke-Olu ni Itirẹ ni Ṣurulere ni o ngbe nisisiyi.

Ọgbẹni Cole ni o to iwọn odun mẹwa nisisiyi ti iyawo on na wa ba on ni ilu Oyinbo. O ni on ma nlọ si ibi iṣẹ ni alalẹ, on si fi iyawo on ti o ntọ ọmọ ọmọ oṣu mẹta lọwọ nile pẹlu ọmọ ọdun meji ti alarede na bimọ le.

Nigbati on pada wa sile on ko ri iyawo on ninu iyara a fi awọn ọmọ ti o tẹ silẹ lori bẹdi ibusun, nibiti o gbe nwa a kiri ni on lọ rii ti o sun si iyara pẹlu ọkunrin kan ti nwọn npe ni Dosun Majẹkodunmi ti awọn jọ ngbe ni adugbo kan na ni ilu Oyinbo.

Ọgbẹni Cole ni tẹlẹtẹlẹ on ti ngbọ wipe ti on ba ti jade nile ni iyara Ologbe Disun Majẹkodunmi lọ lati lọ ṣe igbadun lọdọ rẹ, o ni nişe ni iyawo na lọgun mọ on wipe oruka arede ni gba on ko gbelẹha rara. O ni ki ọkọ on ma se on mọle pa

Ọkọ alarebe na on niran alẹ ọjọ kan ti iyawo on Ọmọlayajọ yi fi on silẹ, ti o lọ sode ownrọ ọjọ keji ni o to pada de nigbati on si bi i lere wipe kinni o fa a, o ni ki on ma pa on laya rara nṣe ni iyawo na ba palẹmọ ti o kuro nile patapata.

O ni ọmọ meta ni iyawo alarede bi fun on, eyi agba ti lọ sile ọkọ ni ilu Oyinbo. O ni iya awọn ọmọ on na dẹ awọn Ọlọpa Dahomey si on wipe ki nwọn mu on, on ko on lẹru lọ ninu ile Ọgbẹni Cole lori on ni o yo on lọwọ awọn ọlọpa na, on ni lati ṣe alaye fun wọn wipe iyawo alarede on ni, nṣe ni o fẹ ko wahala ba on.

**E Ka**
**Oro Alufa Atilade loju ewe keta**


E polowo

Oja yin sinu iwe irohin Eleti-Ofe

To kun fun irohin aladun

Losose



For Your Safety




MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (E.B.) IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA.

— *Sub-Distributors* —

ARMEL'S TRANSPORT LTD.

BENIN-CITY, ONITSHA, ABA.

# Olowo Nda Bira



Awọn alamojuto Ijọba ilu Gẹsi nda bira. Boya ẹ le sọ wipe Kiniṣe ti a fi sọ iru ọrọ bayi: Awọnan ile onipẹtẹsi alakọle oni ọkẹ aimoye ti owo yi ni o jẹ ki a sọ bẹ ẹ. Ori ilẹ kan ti o ti jẹ ira Erith, Kent ni England ni nwọn kọ ọ si. A gbọ wipe gbogbo ile ti nwọn kọ sibẹ a gba Ọke kan o le ẹgbẹdọgbọn awọn Oyinbo ti ko ri ile gbe.

A gbọ wipe awọn kansilọ Ijọba ibilẹ ilu London ni nwọn ṣe eto ile kiko sori ira na fun awọn ara ilu ti ko ri ile gbe, ti gbese owo hihaya fẹ pa wọn.

Ẹnyin kansilọ ilu Eko, ọrọ re o! A fe ki ẹnyin na fori kọ, ki ẹ wa ọna ti ọrọ wahala ile-gbigbe yio ṣe rọ ara ilu lọrun.

ṣe iwọn iṣẹ ti on ba le ṣe lori awọn enia kika na. Sardauna tun ṣe alaye fun awọn enia ti o mba sọrọ wipe gbogbo agbaiye ni nwọn fẹ mọ bi enia ti pọ to ni ilẹ Nigeria.

## Alo o?

(1) Ọpa toro kalẹ o kan ọrun.
(2) Ikoko kekere fidi ti igbẹ.
(3) Ojo rọrọ ko dele onikolo' onikolo sọpe on ni omi ti on lọtọ.
(4) Takiti takiti oke Ibadan o ta ni igba mẹta rẹ yọ.
(5) Gbogbo igi so likatan ko so.
(6 Omidan toro so gẹgẹ yi ọrun ka.
(7) A mu agbo dudu lọ sodo, o di funfun.
(8) Ojiji fi aro igba aṣọ ma balẹ.
(9) Ẹiyẹ binti fo igba igi.
10) Ọra pin si meji ẹnikan ni ri

### ITUMO

(1) Ọjo
(2) Igbin
(3) Agbọn
(4) Ẹyin Ọpẹ
(5) Ọpa-un
(6) Ibẹpẹ
(7) Ọṣẹ dudu
(8) Ọpẹ
(9) Ọju
(10) Ṣokoto

Obo Ko Si N'dere:

## Awon Hausa Mura Giri Fun Enia Kika

KADUNA—Awọn Hausa ni Oke Ọya ni oju awọn ti ... an idagba soke ti olukulnku ndu fun ilu bẹ, ... Ọbọ Jagido kan ko si ni Idere mọ, ọkan na ti ... nibẹ ẹwu-ẹtu ni o nwọ kakiri arin ilu nitorina awọn ... mura silẹ fun gbogbo awọn enia ti nwọn fẹ fi ... mẹta ka ni ilẹ Nigeria ninu oṣu ti mbọ yi.

Ọ... Ahmadu Bello Olatu ... Ijọba Ariwa ni on fẹ k gbogbo awọn minista ati awọn oṣelu wọn lọ di ara wọn ni amure daradara ki wọn mura lati lọ si igeri o lati lọ ṣe alaye fun awọn ara ilu nipa awọn enia ti nwọn fẹ ka kakiri.

Ọlọla Ahmadu Bello ni or ... o de ilẹ yi ko uṣe ... bọ mọto ayọkẹlẹ ṣe faji kakiri arin ilu, o ni bi o ṣe mọto akẹru tabi awọn mọto BỌLẸKAJA ni ki gbogbo wọn wọ wọn lọ si arọko ilu Hausa lọ ṣe ikede fun awọn ara oko ti nwọn mbẹ Ipinlẹ Ariwa ki nwọn jẹki awọn akọwe ka awọn ... anfani ti o wa nibẹ.

Sardauna Sokoto ni on paapa yio bọ ṣokoto

YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE
(NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA
At your service
• STOCK
• SPECIAL ORDERS
• TECHNICAL INFORMATIONS

# Omo Kan Nfero Mi

STOCKHGLMI— Awọn dokita Oyinbo se nkan ara fun ọmọde kan ẹni ọdun mẹdogun ti orukọ rẹ njẹ Christain Olesen, ti nwọn ni agbara mimi ẹmi rẹ ko to fun un.

Nk n ara ti awọn dokita Oyinbo na ti n se ni wipe ẹrọ kẹkere kan nwọn ni waya batiri ẹlẹtiriki si ti nwọn ran ọmọ na 'aya, ti o ba si ti nmi batiri yi pelu waya ẹlẹtiriki a ma se iṣẹ lara rẹ.

A gbọ wipe o ti di ọdun meji gbako n s si ti awọn dokita na ti se iṣẹ yi tuu un, ṣugbọn nwọn mu ọmọ na lọ si ile iwosan awọn dokita na lana fun ibẹwo, nwọn ni o yẹ ki nwọn yẹ ẹ wo boya diẹ ninu awọn waya ti awọn ta sara rẹ, ti nye diẹdie nitoripe ọkan ọmọ na ko lu kiki bi o ti nlu mọ.

Awọn dokita na si wa lẹnu wipe wọn nwo ọna bi o ba wa jaiye ni nko ba nse abiku agba.

## Britain's First Space Craft



**The first all-British setellite, U. K. 3, is scheduled for launching in 1966 carrying five scientific experiments into a circular orbit 400 miles above the earth.**

## Awon Tisa Ti O Ju Ise Sile Pada

CONGO—Ogunlọgọ a w ọ n tiṣa ilu Congo t i nwọn ti fi igba kan da iṣẹ s l i a gbọ wipe nwọn ti pinnu lati pad si ibi iṣẹ wọn ni ara n i g b a ti awọn onilaju kan dide si ọ r ọ awọn tisa na pẹlu awọn alakoso Ijọba ilu na,

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ nipa nkan ti o a sababi dida iṣẹ silẹ na, a gbọ w to iwọn nkan bi oṣu mẹfa n s ti awọn tiṣa olukọni na ko ti ri owo oṣu wọn gba rara.

Nitorinabati ebi bẹrẹsi pa awọn ọ m ọ ati iyawo wọn, nwọn fi ọrọ na sun awọn alakoso Ijọba wipe a w ọ n koi ro o iṣẹ awọn gba lọdọ awọn alakoso ile igbimọ ti n w ọ n n i lati san owo fun awọn.

O le ni ọ k ẹ k a n o le ẹdẹgbajọ ( 35,000 ) awọn tisa na ti nwọn binu fi s silẹ lọkunrin ati lobinrin, sugbon nwọn ti pinnu lati pada sẹnu iṣẹ nigbati nwọn ni nwọn yio s a n abọ owo oṣu wọn fun wọn ninu oṣu yi.


E ma ka

**Iwe Irohin**

**Eleti-Ofe**

**To kun fun irohin aladun**

Losose

Brandt in Great Britain:

# 'Germans' Wish to Live Together as a People'

SCARBOROUGH—When well-meaning people speak of the 'reality' of divided Germany, they are understanding the deeper going reality of a divided people, This is the message that Berlin's Governing Burgomaster took to Great Britain last weekend.

Amid stormy applause, Mayor Brandt told 2,000 delegates to the convention of the British Labour Party in Scarborough.

"I know that the motto 'all or nothing' will no help us. But I earnestly urge my British Friends to recognise the wish and the will of an arbitratily divided people and to see in it a reality too."

West Berlin's Lord Mayor is a leading candidate for the Chancellorship if the Social Democrats should win a Federal election. He told his Labour colleagues of Britain that the regime in Germany's Soviet Zone is most backward in the entire East Bloc.

Returning to the theme of 'reality' and Germany's wish for reunification, Herr Brandt said: 'What is right cannot be wiped off the agenda simply because it cannot be realised today.'

The Sovie Zone of Germany amounts to a special kind of colonial regime, said Brandt, and as such it cannot last. The deputy chairman of the Social Democratio Party added.

'I am thankful that our British friends want to help us by means of gradual changes to improve the situation of the people behind the wall and the barbed wire in Berlin and in partitioned Germany.'

He pointed to numerous foreign-policy parallels between the Garman Socialist and British Labour parties. He said both British and Germans are in favour of a stronger United Nations; armament control and limitation, and the continued fosteriug of NATO as an alert aud fit instrument of defence.

# Hurricane Relief for Caribbean

Aid to the hurricane-stricken Caribbean Islands of Tobago and Haiti is mounting rapidly.

In London yesterday, Monday, the British Red Cross announced that in addition to assistance already provided, they have now aecievee £,000 from O X F A M. the– Oxford Committee for Famine Relief emergency work in Tobago; £1,000 from the "War on Want" organisation; and 3,300 from the League of Red Cross Societies in Switzerland.

The Salvation Army has drawn £1,000 for relief work in Haiti and and has permission to drawn another £1,000 for relief work in Cuba if ti proves necesary. The British Red Cross has also cabled £1, 000 for relief in Haiti.

The Red Cross has also flown out to Tobago 2,000 blankets and tons of emergency clothing provided by the Women's Voluntary Service in London.

The St John Ambulance Brigade in London said today that their emergence relief team in T o b a g o now numbers 25. Reports from the field states that so far they have t r e a t e d 500 casualties in addition to carrying out rescue work and providing food and shelter f o r homeless victims.

**Read**

**And**

**Advertise**

**In**

**Eleti–Ofe**

# Flying Doctor Thanks British Fund-Raiser

LONDON—Dr. Neil Duncan, the "Flying Doctor," operating in Northern Nigeria, recently landed his light aircraft at Hawarden, North Wales Airport–not this time to attend the sick but to receive a commemorative plaque.

The plaque is to be placed on a two-way radio telephone sat at his dispensary at Shinkafe, was officially presented to Dr. Duncan by Mr Frank Brotherton, Chairman of the Llandudno Branch of the English-speaking union of the Commonwealth, which raised £200 for the radio-telephone set already installed at Shinkafe.

The Branch raised the money by holding coffee parties and fetes. Yesterday they again met Dr Duncan's wife, Joan, whose talk to the Branch originally inspired them to make their contributions to the Flying Doctor Service.

Dr. and Mrs Duncan are currecently undertaking a 'whistle-stop tour" of Britain saying a personal "thank-you" to the people who have contributed to the Service. Yesterday they flew from Blackpool to Harwarden in their single-engine Cessna a gift from the Oxford Committee for Famine Relief.

After attending a meeting at the British Medical Association House in London on October 11, the Duncans will make the 4,000 mile flight to Nigeria in the Cessna piloted by an ex-R.A.F pilot. Tom Lampit.

# Ijoba Torunbo Pakute

O bẹrẹ loju ewe kinni)

Ẹnikan ninu awọn ọga awọn ọmọ ẹgbẹ na ni gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ mehaya ti o wa ninu awọn ẹgbẹ na ju ọkẹ marun enia (1000,000) lọ; nwọn ni awọn ọmọ ẹgbẹ t'Eko jẹ ọkẹ kan ati abọ (30,000) enia.

Ninu awọn ọga ẹgbẹ na sọnu foro sọ fun akọwe onirohin wa wipe awọn ti ran enia kakiri ojule l'Eko lati sọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ awọn nkan ti nwọn ni lati ṣe lori ọrọ owo-ile sisan na.

Ati wipe awọn ti ntẹ jẹ hiha kakiri lori ọna ti awọn yio gba boya awọn alamojuto eto Ijọba ko ni bawọn ro ọrọ na ṣe.

Awọn ọmọ ẹgbẹ mehaya ile yi ni ọrọ owo ile jẹ nkan pataki ti awọn fi da iṣẹ silẹ ni oṣu ti o kọja, o si tun jẹ ọkan pataki ti awọn fẹ ki awọn aṣiwaju awọn ro mejọ niwaju awọn ti nwọn fẹ ṣe iwadi nkan ti o mbi awọn ninu.



Malam Yar' Adua

Ewo Lewo o, minisita eleto ilu Eko nipa ọrọ owo ile ti awọn oṣiṣẹ ni awọn fẹ ki nwọn din ku?

## Owo Ile Mehaya Fe Da'ja Sile Larin Awon Oga Osise

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Nwọn ni ti awọn aṣiwaju awọn yi ko ba ie e wa ọna ti nwọn yio gba fi fi ọrọ owo-ile ti awọn ie ki Ijọba fi ofin geku yi sii, awọn yio mọ iru sẹriya ti awọn yio da fun wọn.

Ni oru ana ni ogunlọgọ awọn osiṣẹ pe sinu ile kan Sango l'Ebute-Mẹta lati ro ọrọ ti o fẹ da ija silẹ na.

Ọkan ninu awọn aṣiwaju awọn ọmọ ẹgbẹ oṣiṣẹ ti orukọ rẹ njẹ Samuel Bas-eyi ni ẹjọ awọn oṣiṣẹ jare ti nwọn ni awọn fẹ ba wọn wi lori ọrọ owo-ile hihaya ti o nle si loṣoṣu ti awọn ko ro mejọ fun Ijọba, o ni oju awọn ko fọọ, awọn si mọ atunṣe ti awọn le ṣe lori ọrọ na.

Ẹnikan ninu awọn ogunna gbongbo aṣiwaju ọmọ ẹgbẹ mehaya ile ni ko yẹ ki oju wọn fọ iru ọrọ pataki bayi ara, nkan dabi ẹni wipe awọn fẹ re awọn lẹpa ẹnin ni, bi nwọn ba si ṣe bẹ oju awọn aṣiwaju awọn na yio ri mẹmọ. 'Boya nwọn ti gbagbe wipe awa ni a ran wọn niṣẹ si awọn alamojuto eto iṣẹ Ijọba?'

Mo gbọ wipe baba ẹgbẹ awọn ọmọ ẹgbẹ mehaya ile na ti orukọ rẹ njẹ Ani Molokwu ti tẹ ọkọ leti, o ti gba Ibadan lọ lati lọ ṣe alaye iwa ti awọn aṣiwaju awọn na hu lori ọrọ owo-ile

awọn ni awọn fẹ ki Ijọba fofin de mọlẹ iye owo oṣiṣẹ ti awọn yio ma san fun iyara kọkan bi o ti wu ki iyara na dara to ati awọn ti ko dara tobẹẹ

# Lottery NO. 49 Results

First: No. B00959 won first price £3,000 The second price of £1,000 went to ticket No. L003584 while the third price of £500 was won by the holder of ticket No G0078 56. Other tickets that won price are as follows:

50 PRICES OF £10 EACH

| | | |
|---|---|---|
| C004995: | A009715: | L005350: |
| E007478: | H004512: | E006762: |
| B008335: | I000717: | K002389: |
| J006530: | J009858: | G009072: |
| J001278: | H002467: | E007042: |
| I006135: | G004890: | E004522: |
| C001230: | F003959: | I002183: |
| G003233: | C035141: | B009290: |
| G008086: | N007507: | L007053: |
| E001767: | A008558 | F001442: |
| D009883: | E006376: | I009247: |
| D902904: | L306011: | M009056: |
| G005670: | G004305 | F006495: |
| A002551: | E004795: | N007805: |
| A005526: | L004582 | C002617: |
| F009241: | L007197: | E000966: |
| N007387 | G006971: | |

100 PRIZES OF £5 EACH

# Achara Asoju Ijoba Fowo Taran Nilu Oyinbo

(O bẹrẹ ni oju ewe kinni)

adajọ wipe lọjọ ti o wa sin on lowo ninu oṣu August ibọn ni ọdaran na yọ si on wipe bi on ko ba tete mu owo fun on ibọn ni on yio fi fọ on lori danu.

Obinrin kan Iya afin Inez Thomas ti o wa nibẹ lọjọ na ni nigbati eru ba on ti on fẹ sare jade, o ni ọdaran na ni on ko ba ti on wa rara. O ni on ki pa obinrin, a fi ọkunrin.

A gbọ wipe Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ni Enugu ni ki ọdaran na wa si Nigeria pada.

# Adajo Morgan Ni Yio Se Iwadi Owo Awon Osise

EKO—Ijọba Apapọse l'Eko ti yan Ọgbẹni Adeyinka Morgan tiṣe adajọ Kotu nla ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni Ibadan wipe ki o wa ṣe alaga awọn ti yio ṣe iwadi owo ti awọn oṣiṣẹ ni awọn fẹ ki Ijọba ati awọn oniṣowo fi kun owo awọn.

Ọgbẹni Salubi ọga ile iṣẹ awọn ti o nwa iṣẹ ti o fi igba kan ṣe kọmisanna (alamojuto) Ijọba pajawiri ni Ibadan ni a gbọ wipe nwọn tun yan ati Ogbeni Nwokedi pẹlu Malam kan lati Oke Ọya.

A ko ti mọ igbati nwọn yio bẹrẹsi ṣe iwadi ọrọ na sugbọn a gbọ ti pe awọn oṣiṣẹ ko fẹ ki ọrọ ima na pẹ rara nitoripe inira owo ti o kere ti awọn ngba na pọ ju.

## Akiyesi

Iwe Irohin Eleti-Ofe yio jade lojo Jimo

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Phone 23370 Lagos; Editor: (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosoko Street, Box 457, Lagos.